# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## FÈRÈŞÉ ỌRUN

## Ìtàn ...

**Genesisi 27:1-28**

Jakọbu ko fi ìgbà kankan şe aláìní bẹẹni kò dá nikan wà rí - ìdí si ni pé, o jẹ ọlọgbọn arekereke, tí ó sì jẹ́ onimọ ti ara ẹni nìkan. Jakọbu kọ́kọ́ fun Eşau ni ẹgúnjẹ, ẹniti işe ẹ̀gbọ́n kí ó le ta ogún-ìbí rẹ̀ fún un. Lẹhin náà, pẹlu iranlọwọ́ ìyá rẹ̀, o tún tan Isaaki baba rẹ ti ojú rẹ nşe baibai jẹ, lati gba ìbùkún lẹnu baba rẹ èyí ti o yẹ fun Eşau.

Nibayi, Jakọbu fẹ́ sá kúrò nilé, nitori ki ẹ̀gbọ́n rẹ ma ba pa á. O tẹriba, o si sọkun, nigbati o ri wípé aşiri oun ti tú. Ninu aginju, oun nikan, o mu okúta lati şe ìrọ̀rí rẹ pẹlu ọ̀pá kan fun ààbò. Jakọbu fẹ́ lati sinmi. O ronú pé boya ni oun yio fi rí ojú awọn obi oun mọ́ - ati pé bóyá Ọlọrun yio dari ji oun. Nigbati o rẹ̀ ẹ́, o sùn lọ. Laipẹ, o bá ara rẹ̀ lójú àlá. Ó rí iná nlá kan to njó lati ibi àwọn ọrun ti o sí sílẹ̀, pẹlu àkàsọ̀ daradara kan lati inu ogo lókè ọrun de ori ilẹ̀ ayé nísalẹ̀. Awọn angẹli àìniye sì ngòkè, nwọn si nsọkalẹ̀ lori àkàsọ̀ naa.



©Review and Herald

Nigbana ni Jakọbu sì gbọ́ ohùn Oluwa lati ọ̀run, O sì seleri lati bukun Jakọbu ni ọ̀nà rẹ̀. Oluwa tún fi da Jakọbu lójú pé, ọ̀títọ́ ni ìlérí ti Oun ti şe fun Abrahamu ati Isaaki. Nígbàtí o dìde, o wólẹ̀ lori eekún rẹ̀, o si jẹ́ ẹ̀jẹ́ lati kọ ọ̀nà imọ-tara-ẹni-nikan sílẹ̀. O seleri, "Ati ninu ohun gbogbo ti iwọ o fi fun mi, emi o si fi idamẹwa rẹ̀ fun ọ." Genesisi 28:22.

Ọlọrun gba ẹ̀jẹ́ rẹ̀, O sì sí fèrèşé ọ̀run fun un, ti o fi jẹ́ wípé nígbàtí Jakọbí padà si ilé lẹhin ogun ọdun, o ti di ẹni nlá ati ẹni to ntọrẹ àànú ju bi o ti yẹ lọ.

AMAZING FACTS

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọnyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹşẹ Bibeli kọọkan tán.

1. Níbo ni Jakọbu ti kọ́ lati má a san idamẹwa fun Ọlọrun?

**Genesisi 14:18,20**

Melkisedeki ọba Salemu si mu ounjẹ ati ọti waini jade wá: oun a si ma şe alufa Ọlọrun Ọga-ogo, Olubukun si li Ọlọrun ọga-ogo ti o fi awọn ọ̀tá rẹ le ọ lọwọ. Oun si dá ________ ohun gbogbo fun un.

Àkíyèsí: Ìdámẹwa ni ìdá-kan ninu idamẹwa lori owó to nwọle fun wa. Nitootọ, "ìdámẹwa" tumọ si "ìdá-sí-mẹwa." Baba, baba Jakọbu, Abrahamu fi apẹrẹ lélẹ̀ ni ọ̀pọ̀ ọdún sẹhin nipa fifún Melkisedeki alufa Ọlọrun ni ìdámẹwa.

2. Ìpín melo ninu owó to nwọle fun wa lo yẹ fun Ọlọrun?

**Lefitiku 27:30**

Ati gbogbo ________ ilẹ naa ibaşe ti irúgbìn ilẹ naa, tabi ti eso igi, ti __ ____ni: mímọ́ ni fun OLUWA.

Àkíyèsí: Gẹ́gẹ́ bi ọ̀fin, ìdá ọgọrun ninu ọgọrun ohun gbogbo ti a ni lo yẹ fun Ọlọrun.

**Orin Dafidi 24:1**

Ti OLUWA ni ilẹ, ati ẹkún rẹ̀; ayé ati awọn ti o tẹdo sinu rẹ̀.

Şugbọn Ọlọrun fẹ́ ki a mọ̀ pé ohun gbogbo ti a ni jẹ́ ti Rẹ̀ nipa fifi ìdá-sí-mẹwa fun Un, tabi ìdá mẹwa ninu èrè tí o nwọle fún wa.

3. Kinni Ọlọrun nfi ìdámẹwa wa şe?

**Numeri 18:21,24**

Si kiyesi i, emi si ti fi gbogbo ___________ ni Israeli fun awọn ọmọ Lefi ní ìní, nitori işẹ-ìsìn wọn ti nwọn nşe, ani işẹ́-ìsìn àgọ́ ajọ, Nitori __________ awọn ọmọ Israeli, ti nwọn mú wá li ẹbọ ìgbésọsókè fun OLUWA, ni mo ti fi fun awọn ọmọ Lefi lati ni: nitori naa ni mo şe wi fun wọn pé, Nwọn kò gbọdọ ní ilẹ̀-ìní laarin awọn ọmọ Israeli.

**1 Korinti 9:13,14**

Ẹnyin kò mọ̀ pe awọn ti __________ nipa ohun mímọ́, nwọn a maa ________ ninu ohun ti tẹmpili? Ati awọn ti nduro ti pẹpẹ nwọn a ma şe ajọpin pẹlu pẹpẹ?, Gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀li Oluwa si şe ìlànà pe, awọn ti ___________ ihinrere ki nwọn o si ma jẹ nipa ihinrere.

Àkíyèsí: Ninu Majẹmu Lailai, Ọlọrun paşẹ pé ki idamẹwa wà fun riran awọn ọmọ Lefi lọ́wọ́, awọn to jẹ́ ìrànşẹ Ọlọrun. Ninu ẹ́ Korinti 9:13, Ọlọrun wípé, gẹ́gẹ́ bi awọn alufa atọjọ ti a nşan owó fun lati inu idamẹwa tẹmpili, bẹ́ẹ̀li awọn iranşẹ ihinrere loni, a gbọ́dọ̀ ma a sanwó fun wọn lati inu idamẹwa ti a ba mú wá sinu ijọ.

4. Njẹ́ ètò ìdámẹwa jẹ ara ọ̀fin Mose, èyí ti o parí lórí agbelebu?

**Genesisi 28:20,22**

Jakọbu si jẹ́ ẹ̀jẹ́ wipe, Bi Ọlọrun ba pẹlu mi, ti o si pa mi mọ́ li ọ̀nà yi ti emi ntọ̀, ti o si fun mi li ohun jijẹ, at aşọ bibora, Okuta yi, ti mo fi lelẹ şe ọwọ̀n ni yio si şe ile Ọlọrun: ati ninu ohun gbogbo ti iwọ o fi fun mi, emi o si ______ idamẹwa rẹ̀ fun ọ.

Àkíyèsí: Rárá! Ati Abrahamu ati jakọbu ni wọn san idamẹwa owó wọn fun Ọlọrun, ki a to fún Mose lofin. Ìdí ni pe, wọn ti san idamẹwa wọn, ki Mose to lọ si ori-òkè Sinai, a mọ̀ pé ki işe ara ọ̀fin Mose, èyí ti o dopin ni orí agbelebu. Ọ̀fin idamẹwa jẹ́ ètò Ọlọrun lati ran işẹ́-iranşẹ lọ́wọ́, o şi wà loni.

5. Şùgbọ́n, şe Jesu kò pa ètò idamẹwa sisan run bí?

**Matteu 23:23**

Ègbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi, agabagebe! nitori ti ẹnyin nsan ___________ minti, ati anise, ati kumini, ẹnyin si ti fi ọ̀ran ti o tobiju ninu ofin silẹ laişe, idajọ, aanu ati igbàgbọ́: wọnyi li o _________ ti ẹnyin iba şe, ẹnyin kì ba si fi wọnni silẹ laişe.

Àkíyèsí: Bẹ́ẹ̀kọ́. Jesu ri wípé awọn Farisi jẹ́ onimọtara-ẹni-nikan, ti wọn nyọ awọn kan şẹhin pé idamẹwa wọn ko to nkankan, dípò ki wọn ma gbé ìdamẹwa bí garawa mẹjo wá sí tẹmpili. Nitori naa, ni Jesu fi bawọn wí pé, wọn ti fẹran idamẹwa jù, tí wọn sì kùnà ni idajọ, aanu ati ìgbàgbọ́. Jesu kò da wọn lẹbi nitori pé wọn nsan idamẹwa, şùgbọ́n nitori wọn fi ìlànà Kristiani ti o tobi silẹ laişe. Ìdí niyi ti Jesu fi wípé, "wọnyi li o tọ́ ti ẹnyin iba şe (o nsọ nípa idamọ́ ẹwa), ẹnyin ki bà si fi wọnni silẹ laişe."

6. Kinni ileri iyanu ti Ọlọrun se lori sisan idamẹwa?

**Malaki 3:10**

Ẹ mu gbogbo idamẹwa wá si ile işura, ki ounjẹ ba le wà ni ile mi, ẹ si fi eyí _________ mi wò nisinsinyi, li OLUWA awọn ọmọ ogun wi, bi emi kì yio ba ________ awọn ferese ________ fun nyin, ki nsi tú ibukún jade fun nyin, tobẹ̀ẹ̀ ti kì yio si aye to lati gbà a.

Àkíyèsí: Ọlọrun nsọ pé: "Bi o ko ba siyemeji, kí o má a san idamọ́ ẹwa bi ìdánwò. Ẹ dán mi wò, ki ẹ wa wo bóyá emi kò ni da ibukún si orí yin ni ọ̀pọ̀ yanturu." Ọgurun ninu ẹgbẹrun awọn to nsan idamẹwa ni yio jẹri si pé otitọ ni. O kò le e fun Ọlọrun jù!

7. Ọlọrun sọ fun awọn eniyàn Rẹ pé ki wọn mu gbogbo idamẹwa wọn wá si ile işura. Kinni itumọ èyí?

**Nehemiah 13:12**

Nigba naa ni gbogbo Juda mu idamẹwa ọka ati ọti waini titun ati ororo wá si ___________ .

Àkíyèsí: Ilé işura ni ibi işura ijọ Ọlọrun. (Ilà Bibeli mu ki "ibi işura" ba "ilé işura" mu.") Ninu Malaki 3:10, Ọlọrun pe ilé işura ni "ilé mi", èyí ti işe ijọ Rẹ tàbí tẹmpili. Awọn ẹşẹ Bibeli miran tí ó tún tọka si ilé işura bi tẹmpili, tẹmpili ibi işura ni 1 Kronika 9:26; 2 Kronika 31:11,12 ati Nehemiah 10:37,38. Nitori naa, o wá hàn gbangba bayi pé ilé işura ni ibi işura ijọ Ọlọrun.

8. Nigbati a bá san idamẹwa awọn wo lo ma n gba owó lọwọ wa?

**Heberu 7:8**

Ati nihin, awọn ẹni kíkú gbà idamẹwa; şùgbọ́n nibẹ̀, ___________ a jẹri rẹ̀ pe o mbẹ laaye.

**Kolosse 3:23**

Ohunkohun ti ẹnyin ba nşe, ẹ maa fi tọkantọkan şe e, gẹ́gẹ́ bi fun ___________ , ki si işe fun eniyan.

Àkíyèsí: A gbọdọ ma a rántí nigbàgbogbo pé a ko da idamẹwa fun eniyàn bikoşe fun Ọlọrun. Ti Rẹ ni işe. A kò gbọdọ̀ şe aniyàn nípa bi wọn ti nlo idamẹwa wa, ti o bá jẹ́ wipe Ọlọrun ni a fi fun. Ọlọrun tóbi tó lati bójútó ohun ti işe ti Rẹ̀ ati lati mu ẹnikẹni ti kò ba yẹ ninu şişẹ̀tò owó Rẹ̀.

9. Pẹlu idamẹwa mi ti o jẹ́ ti Ọlọrun, kinni nkan miran ti Ọlọrun tún nbèèrè lọ́wọ́ awọn ènìyàn Rẹ̀?

**Orin Dafidi 96:8**

Ẹ fi ogo fun orukọ OLUWA, mu __________ wá, ki ẹ si wá si agbala rẹ̀.

**Malaki 3:8**
Eniyan yio ha jà Ọlọrun li olè? Ṣùgbọ́n ẹnyin sa ti jà mi li olè. Ṣùgbọ́n ẹnyin wipé, nipa bawo li awa fi jà ọ li olè? Nipa idamẹwa ati ___________ .

Àkíyèsí: Oluwa bèèrè lọwọ wa lati san ọrẹ wa latinu wá lati fi ìfẹ́ wa hàn si I ati lati dupẹ fún ìbùkún Rẹ̀.

10. Èló la gbọdọ san fun ọrẹ?
**2 Korinti 9:7**
Ki olukuluku eniyàn ki o ṣe gẹ́gẹ́ bi o ti pinnu li ___________ rẹ̀; ki iṣe âfẹkúnṣe, tabi ti alaigọdọ má ṣe: nitori Ọlọrun fẹ oninu didun ọlọrẹ.

Àkíyèsí: Bibeli kò sọ iye kan ní pàtó. Olukuluku ènìyàn ni yio pinọ́ nu iye to ba wù ú gẹ́gẹ́ bi ọrẹ atinuwa, bí Ọlọrun bá ṣe darí.

11. Kinni idanwo ti Adamu ati Efa kùnà ninu rẹ ti awa gbọdọ yege ninu rẹ bi a ba fẹ́ wọ ijọba Ọlọrun?
**Genesisi 3:3**
Ṣùgbọ́n ninu eso________nì ti o wá laarin ọgbà Ọlọrun ti wipe, Ẹnọ́ yin kò ___________ jẹ ninu rẹ̀, bẹ́ẹ̀li ẹnyin kò gbọdọ___________ an, ki ẹnyin ki o má ba kú.

Àkíyèsí: Ọlọrun sọ fun Adamu ati Efa pé, wọn le má a jẹ gbogbo eso igi ọgbà, ṣùgbọ́n ẹyọ kan ni wọn kò gbọdọ jẹ - igi ìmọ̀ rere ati buburú. Wọn kò gbọdọ jẹ ninu eso igi naa tabi ki wọn fi ọwọ́ kan an. Ọlọrun kò sì fi ọgbà iná yí igi náà ká. Ọlọrun yàn lati fi igi náà pamọ́ sí ibi ti ọwọ́ wọn ti lè tó o. Wọn sì fi ọwọ́ kàn án, nítoripe wọn kò gba Ọlọrun gbọ́. Loni, Ọlọrun nfún wa ní idánwò kan náà. Ó wípé, "O le e pa gbogbo owó tí o nwọle fun ọ mọ́, ṣùgbọ́n idamọ́ ẹwa ni o kò gbọdọ kó pamọ́. Temi ni owó naa. Maṣe mu." Nitori naa, Ọlọrun fi silẹ̀ nibiti ọwọ́ wa le ti to o, kí a sì mu, bi a ba fẹ́. Ṣùgbọ́n bi a ba se bẹ́ẹ̀, a tún ndá ẹ̀ṣẹ̀ kanna ti Adamu ati Efa ti dá. Ọlọrun kò nilo eso igi kan nípàtó. A dan ododo wọn wò ni. Bẹẹni kò fẹ idamẹwa wa. Ọlọrun lo ni ohun gbogbo! O jẹ́ idanwo ìfẹ́ wa, otitọ ati ìgbàgbọ́ wa.

12. Bi a ba kọ̀ lati san idamẹwa ati ọrẹ fun Ọlọrun, òfin wo ni a n rú?
**Malaki 3:8**
Eniyan yio ha jà Ọlọrun li _________? Ṣùgbọ́n ẹnyin sa ti ________ mi li olè. Ṣùgbọ́n ẹnyin wipé, nipa bawo li awa fi jà ọ li olè? Nipa idamẹwa ati ọrẹ.
**Eksodu 20:15**
Iwọ kò gbọdọ _________.

Àkíyèsí: Ọlọrun sọ pé awọn ti wọn mọ-ọn-mọ ti wọn jẹ́ alaisootọ ninu idamẹwa ati ọrẹ jẹ́ olè. O jẹ ohun burukú ti ẹnikan ba ja ẹloọ́ miran lolè, ṣùgbọ́n o jẹ́ èrò tó burú jù ti eniyàn bá fẹ́ ja Ọlọrun lólè! O jẹ́ ohun to ṣoro lati gbàgbọ́ pe awọn eniyàn tún ngbiyànjú lati ji owó ti Ọlọrun ti yàn lati kede ihinrere fun awọn to nù.

13. Kinni Ọlọrun sọ wipé yio ṣẹlẹ̀ si awọn ti wọn mọ-ọn-mọ ja Oun lolè idamẹwa ati ọrẹ?
**Malaki 3:9**
___________ li a o fi nyin ré; nitori ẹnyin ti jà mi li olè, ani gbogbo orilẹ-èdè yi.
**1 Korinti 6:10**
Tabi awọn ___________ , tabi awọn olojúkòkòrò, tabi awọn ọmuti, tabi awọn ẹlẹgàn, tabi awọn alọnilọ́wọ́gbà ni yio jogun ijọba Ọlọrun.



Àkíyèsí: Awọn ti kò bá jẹ́ olootọ ninu idamẹwa ati ọrẹ ni a ti fi gegun, bí kò ba ṣe pe wọn yipadà, a o le wọn jade ni ijọba Ọlọrun gẹ́gẹ́ bi olè.

14. Kini ìdí ti ojúkòkòrò fi jẹ ewu?
**Luku 12:34**
Nitori nibiti ___________ nyin gbé wà, nibẹ̀ li ọkàn nyin yio gbé wà pẹlu.

Àkíyèsí: Ojúkòkòrò le pa ènìyàn nitori ọkan wa ma nwà nibi nkan tí a bá fi pamọ́. Ti o bá jẹ ìnọ̀gà mi lati má a re owó jọ titi, ọkàn mi yio ṣe ojúkòkòrò, ọkanjua àti onigberaga. Ṣùgbọ́n bí o bá jẹ ìnọ̀gà mi ni lati gbé iṣẹ́ Ọlọrun sókè, ọkan mi yio ma a ṣe ìtọ́jú, ni ìfẹ́, di ominira ati ìrẹ̀lẹ̀. Dandan ni, ibi iṣura wa ni ọkàn wa má a wà. A kò gbọdọ gbagbe pé imọtara-ẹni-nikan ati ìfẹ́ owó ti Judasi ní, lo mú kí ó ta Jesu ni ọgbọ̀n owó idẹ fadaka (Matteu 26:14-16).

15. Bawo lo ṣe rò pé yíò ti rí li ára Jesu nigbàtí a ba ja Á lolè idamẹwa ati ọrẹ?
**Heberu 3:10**
Nitori naa inu mi ___________ si iran naa, mo si wipe, Nigba gbogọ́ bo ni nwọn nṣìnà li ọkàn wọn; nwọn kò si mọ̀ ọ̀nà mi.

Àkíyèsí: Jesu yio ṣe gẹ́gẹ́ bi obi ti ọmọ rẹ ji owó mu ninu apò rẹ. Ṣisọ owó naa nu ki iṣe ohun to lagbara, Bikoṣe ti pe ọmọ naa ko ni ìwà rere, bẹẹni kò ní ìfẹ́ ati ifọkàn-tán, tí o sì bani ninu jẹ́ gidigidi. O dájú pe kò si ẹni to fẹ́ mu inú Olugbala wa bàjẹ́.

16. Kinni ìlànà Bibeli miran ti Ọlọrun sọ nipa ìfifún-ni?
**A. 2 Korinti 8:5**
Ati eyi, ki iṣe bi awa ti rò ri, ṣùgbọ́n nwọn tètèkọ́ fi awọn tikara ________ fun Oluwa, ati fun wa, nipa ifẹ́ Ọlọrun.
**B. Owe 3:9**
Fi ohun-ìní rẹ bọ̀wọ̀ fun OLUWA, ati lati inú gbogbo _________ ibisi-oko rẹ.
**D. Owe 11:24,25**
Ẹnikan wà ti ntuka, sibẹ o _________ si i, ẹnikan si wà ti nháwọ́ jù bi o ti yẹ lọ, ṣùgbọ́n kìkì si aini ni, Ọkan ___________ li a o mu sanra; ẹniti o mbomirin ni, oun tikararẹ̀ li a o si bomirin pẹlu.
**E. Iṣe Awọn Aposteli 20:35**
Ninu ohun gbogbo mo fi apẹrẹ fun nyin pé, nípa ṣiṣe iṣẹ́ bẹ́ẹ̀, o yẹ ki ẹ maa ràn awọn alailera lọ́wọ́, ki ẹ si ma ranti ọ̀rọ̀ Jesu Oluwa, bi oun tikararẹ̀ tì wipe, Ati ___________ o ni ___________ jù ati gbà lọ.
**Ẹ. Luku 12:21**
Bẹ́ẹ̀ li ẹniti o to iṣura jọ fun _________ rẹ̀, ti kò si li _________ lọdọ Ọlọrun.
**F. Luku 6:38**
Ẹ fi fun ni, a o si fi fun nyin; oṣuwọn daradara, akimọlẹ̀, ati amipọ̀, ________ __, li a o wọ̀n si àyà nyin; nitori oṣuwọ̀n naa ti ẹnyin fi wọ̀n, oun li a o pada fi wọ̀n fun nyin.
**G. 1 Korinti 16:2**
Li ọjọ́ ikinni ọ̀ṣẹ̀, ki olukuluku nyin fi sinu iṣura lọdọ ara rẹ̀ li apakan, gẹgẹ bi Ọlọrun ti ṣe ___________ fun un, ki o máṣe si ikojọ nigbati mo ba de.
**GB.Deuteronomi 16:17**
Ki olukuluku ki o mú ọrẹ wá bi agbara rẹ̀ ti to, __________ bi _________ OLUWA Ọlọrun rẹ ti o fi fun ọ.



Àkíyèsí: Ìdá mẹsan ninu idamẹwa owó to nwọlé fun mi pẹlu ibùkún Ọlọrun tó funmi ju gbogbo mẹwẹwa lọ tí kò ni ibùkún Ọlọrun ninu. Bí Ọlọrun ba déédé si fèrèṣé ọrun, gbogbo ibukún Ọlọrun ki ifi gbogbo ìgbà jẹ owó. Ìbùkún Ọlọrun le e jẹ ilera tó péye, alaafia ti ọkàn, idahun adura, ààbò, ẹbi alayọ̀, okun, agbara lati gbé igbẹṣẹ ọlọgbọ́n, ìrẹ́pọ̀ pẹlu Jesu, aṣeyori ninu ìjèrè-ọkàn, ọkọ̀ to ti gbó ki o má a sáré, ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bi a ba fẹ́ràn Jesu lotitọ, ṣiṣe iṣẹ́ Rẹ ko ni jẹ àjàgà fun wa. Dipo àjàgà, ìbùkún ni yio jẹ́ - anfaani ologo ti a o fi ṣe é pẹlu ayọ nla ati ìtẹ́lọ́rùn.

17. Kinni àkàsọ̀ ti Jakọbu ri lójú àlá rẹ̀ dúró fún?
**Johannu 1:51**
O si wi fun un pe, Lootọ, lootọ ni mo wi fun nyin, Ẹnyin o ri ọrun ṣí silẹ, awọn angẹli Ọlọrun yio si ma gòkè, nwọn o si ma sọkalẹ sori _________ _______.

Àkíyèsí: Jakọbu ri àkàsọ̀ ti o duro lori ilẹ̀ ti orí rẹ si de òkè ọrun, èyí tí ó dúró fún Ọmọ eniyan. Ninu Malaki 3:10, Ọlọrun wipé bi a ba le e mu gbogbo idamẹwa wá si ilé iṣura, Oun yio sí fèrèṣé ọrun silẹ̀ fún wa yio si tú ibùkún ti a kò le gbà tán fún wa! Jesu ni ìbùkún náà.

18. Ẹ̀bùn wo lo ga jù ti a le fi fún Jesu?
**Owe 23:26**
Ọmọ mi, fi __________ rẹ fun mi, ki o si jẹ ki ojú rẹ ki o ni inu-didùn si ọ̀nà mi.
**Marku 7:6**
O dahùn o si wi fun wọn pe, Otitọ ni Isaiah sọtẹlẹ nipa ti ẹnyin agabaọ́ gebe, bi a ti kọ ọ pe, Awọn eniyan yin fi ètè wọn bọla fun mi, ṣùgbọ́n _________ wọn jìnà si mi.

Àkíyèsí: Bi Jesu ba ni ọkàn wa, Oun ni o ni ohun gbogbo pẹlu.

# Èsì Rẹ

Nígbàtí a ba jẹ́ olotítọ́ nínú idamẹwa ati ọrẹ wa, Jesu yio di ẹnikeji wa ninu ohun gbogbo ti a ba fẹ ṣe ni áyé wa. Ṣe o fẹ́ pe Jesu lati di ẹnikeji rẹ nipa sisan idamẹwa ati ọrẹ rẹ?

IDAHUN: ______________.

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ̀ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678